# ỌJỌ IBI KRISTI KIN-IN-NI

## Matteu 2:1-23; Luku 2:1-20

## ẸKỌ 417 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Má bẹ̀ru: sawò o, mo mu ihin-rere ayọ̀ nla fun nyin wá, ti yio ṣe ti enia gbogbo" (Luku 2:10).**

**Awọn Olubẹwò Lati Ọrun**

Ọjọ-ibi Kristi kin-in-ni, ti a ṣe ajọyọ̀ rẹ̀ ni ọpọlọpọ ọdun sẹyin ni ilu kekere nì, Bẹtlẹhẹmu, mú ki awọn olubẹwò ti Ọrun sọkalẹ wá si ori-oke Judea. Iró orin awọn angẹli bẹ̀rẹ si i dún ninu awọsanma; awọn oluṣọ-agutan ti n gbọ́ si wi pe gbogbo ọrun kún fun ẹgbẹ́ angẹli ti n kọrin. Ẹgbẹ́ ogun Ọrun ni o sọkalẹ wá lati kọrin pe "Ogo ni fun Ọlọrun loke ọrun," nipa Olugbala arayé ti a bi ni oru ọjọ naa ni Bẹtlẹhẹmu.

Awọn angẹli ti mọ Jesu ni Ọrun, wọn si ti n sìn In wọn si n wolẹ fun Un bi wọn ti n kọrin yi itẹ Rẹ̀ ká. Olukuluku ẹni ti o wà ni Ọrun ni o layọ, kò si si ohun kan nibẹ ti o le pa wọn lara. Ṣugbọn ni ọjọ kan Ọlọrun bojuwo ayé O si ri gbogbo ibanujẹ ati oṣi ti o wà nibẹ O si pé akoko tó fun Jesu lati sọkalẹ lọ sibẹ lati ran awọn eniyan lọwọ.

**Aigbọran ati Wahala**

Ayé paapaa ti jẹ́ ibi ayọ̀ tẹlẹ ri; ohun ti o si ṣẹlẹ ni yii. Dipo ti awọn eniyan iba fi gbọran si aṣẹ Ọlọrun, wọn yipada kuro lọdọ Rẹ̀ wọn si ti dá oriṣiriṣi ẹ̀ṣẹ. Nitori naa ni wahala ṣe wà ni ayé dipo ayọ̀. Nipa ṣiṣe aigbọran si Ọlọrun awọn eniyan ti ta ara wọn fun Satani, wọn ki i si i ṣe ọmọ Ọlọrun mọ́. Kò si si ohunkohun ti wọn ni ti o le san owo igbese ẹ̀ṣẹ wọn. Ẹni kanṣoṣo ni Ẹni ti o le rà wọn pada, tabi ki o san owo fun idasilẹ wọn. Ẹni naa ni Jesu.

**Ayọ̀ Nla fun Gbogbo Eniyan**

Nitori naa nigba ti Ọlọrun ri ibanujẹ ti o wà ninu ayé ti O si wi pe akoko tó fun Jesu lati lọ gẹgẹ bi Olurapada, Jesu wá a si bi I ni ibujẹ ẹran ni Bẹtlẹhẹmu. Njẹ iwọ mọ idi rẹ̀ ti awọn angẹli fi kún fun ayọ̀ bẹẹ? Inu wọn dùn pupọ pe Ọlọrun la ọ̀na yii silẹ fun awọn olugbé inu ayé lati tun ni ayọ̀.

Ẹru ba awọn oluṣọ-agutan nigba ti wọn ri awọn angẹli. Boya wọn rò pe awọn yoo kú. Ṣugbọn aṣiwaju awọn angẹli naa kọ si wọn pe: "Ma bẹ̀ru, sawò o, mo mu ihinrere ayọ̀ nla fun nyin wá, ti yio ṣe ti enia gbogbo. Nitori a bi Olugbala fun nyin loni ni ilu Dafidi, ti iṣe Kristi Oluwa." Nigba yii ni awọn ẹgbẹ́ akọrin angẹli naa bẹ̀rẹ si orin iyin ti o n dún: "Ogo ni fun Ọlọrun loke ọrun, ati li aiye alafia, ifẹ inurere si enia." Abajọ ti awọn angẹli n kọrin! Ọsọ ti o dara jù lọ ni Ọrun ti sọkalẹ wá si ayé lati wá bá awọn eniyan gbé, ati lati kọ́ wọn bi a ti i gbé. Igbagbọ́ ninu Rẹ̀ yoo mú alaafia wá sinu ọkàn ẹnikẹni ti o gbagbọ́. Bẹẹni ẹbọ fun ẹ̀ṣẹ, ani Ọdọ-Agutan Ọlọrun, si fi tayọtayọ, fi ara Oun tikara Rẹ̀ fun eniyan, lati rà wọn pada sọdọ Ọlọrun.

**Titẹsilẹ**

A kò mọ̀ bi ẹlomiran tun gbọ́ orin awọn angẹli nì yatọ si awọn oluṣọ-agutan; ṣugbọn awọn ẹni irẹlẹ wọnyii bẹ̀ru Ọlọrun wọn si ni ọkàn ti o le tẹtisilẹ lati gbọ́ iṣẹ ti a rán lati Ọrun. Ẹnikẹni ti o ba n fẹ́ gbọ́ Ọlọrun yoo bá a sọ̀rọ. A le ṣe alaigbọ́ ọ ni ọ̀na ọ̀rọ sisọ gan, ṣugbọn ọkàn wa yoo mọ ohun ti Ọlọrun n fẹ́ bá wa sọ bi a ba rin pẹ̀lẹ niwaju Rẹ̀, ti a si fiyesi ohun ti O n fẹ́ bá wa sọ. Ọpọ igba ni o jẹ́ pe bi a ba ka Bibeli, awọn ẹsẹ miiran a hàn si wa gbangba ti yoo fi dabi ẹnipe awa gan ni Ọlọrun n ba sọ̀rọ lojukoju.

A kò le sọ bi Maria ati Josẹfu gbọ́ orin awọn angẹli nì, ṣugbọn awọn oluṣọ-agutan sọ gbogbo ohun ti wọn ti gbọ́ fun wọn. Maria mọ̀ pe Ọmọ Ọlọrun ni Ọmọ ti oun bi, bi o tilẹ jẹ pe kò sọ ohunkohun nipa rẹ̀, o "pa gbogbo nkan wọnyi mọ́, o nrò wọn ninu ọkàn rẹ̀." Iṣura iyebiye ni o jẹ́ fun un lati mọ̀ pe awọn angẹli ti kọ orin ogo nipa ọmọ rẹ̀.

**A Ri Alaafia Gbà**

Wò iru ayọ̀ ati alaafia ti awọn oluṣọ-agutan ti o ri Jesu ni! Wọ́n pada si idi iṣẹ irẹlẹ wọn, iṣẹ wọn si rọrun fun wọn ju ti atijọ lọ nipa ayọ̀ ti o wà ninu ọkàn wọn. Wọn ti ri Jesu, Olurapada ayé! Wọn ti lọ wolẹ sìn niwaju Rẹ̀, wọn si pada pẹlu ibukun.

Awọn oluṣọ-agutan wi pe awọn angẹli ni o tọka ibi ti a bi Olugbala si, "ti iṣe Kristi Oluwa" fun wọn. Olukuluku ẹni ti o gbọ́ ni o n yalẹnu; ṣugbọn a kò mọ̀ bi ọpọlọpọ ni o lọ lati fi oju awọn tikara wọn ri i.

Ọpọlọpọ eniyan lode oni ti o n gbọ́ nipa itan Irapada ni o n jẹ́ ohun iyanu fun pe a le dari ẹ̀ṣẹ awọn eniyan jì wọn, ki igbesi-ayé wọn si yipada, ati pe alaafia ati ayọ̀ le dipo ikoro ọkàn ati ikorira; ṣugbọn wọn kò gbiyanju lati ri Jesu. Nitori naa wọn kò ri alaafia ti Oun i ma fun gbogbo ẹni ti o tọ̀ Ọ wá lọfẹẹ.

### Lati Ilẹ Jinjin Réré

Bi o tilẹ jẹ pe diẹ ninu awọn eniyan ti o wà ni Bẹtlẹhẹmu wá wo Jesu ni alẹ ọjọ yii, awọn amoye kan ti o wà ni ilu ti o jinna réré kan gbọ́ nipa ọjọ-ibi Rẹ̀, wọn si rin irin-ajo lati ọna jinjin wá lati ri I. Wọn ki i ṣe awọn Ju ti wọn n reti Messia, ṣugbọn wọn n fi ọkàn otitọ wá ohun kan ti o niyelori jù ti o si le wà pẹ titi ju eyi ti ọgbọ́n ti fifun wọn lọ. Laisi aniani, wọn kò ni ṣalai ti kà ninu ẹ̀kọ́ wọn nipa asọtẹlẹ Balamu ẹni ti Ọlọrun misi lati wi pe: "Irawọ kan yio ti inu Jakọbu jade wá, ọpa-alade kan yio si ti inu Israẹli dide" (Numeri 24:17).

Awọn amoye wọnyii jẹ́ eni ti o kẹkọọ nipa awọn irawọ, lalẹ ọjọ kan wọn ri imọlẹ nla kan ni oju ọrun irú eyi ti wọn kò i ti ri ri. O ha le jẹ pe Ọlọrun n fi àmi kan hàn fun ayé pe Messia Israẹli ti dé? Ọkàn wọn gbiná, wọn si dide lati tẹle irawọ Bẹtlẹhẹmu.

### Wiwo

Boya ẹnikẹni ti o ba woke ni i ba ti ri abàmi irawọ yii, ti i ba si tẹle e lọ si ọdọ Olugbala; ṣugbọn awọn amoye diẹ wọnyii nikan ni a mọ̀ nipa rẹ̀ ti n fi oju sọna fun nnkan ayeraye, ti wọn si tẹle irawọ naa titi dé ibi ti a bí Ọba Ogo si.

Wọn rin irin-ajo la aṣalẹ̀ já, wọn n ré awọn odò kọja, wọn si n gun awọn òke kéekeèkeé, bẹẹni wọn tẹjumọ irawọ naa titi wọn fi dé ilu Jerusalẹmu nibiti ọba n gbé. Ijọba Romu ni o yan ọba yii ki i si ṣe ọba Israẹli lati idile Dafidi. Awọn wolii ti kọ akọsilẹ pe Messia naa yoo ti idile Dafidi wá, nitori eyi awọn amoye n reti pe Messia naa yoo jẹ́ ọba, wọn si lọ si olu-ilu awọn Ju lati wá a.

### Jerusalẹmu Daamú

Lode oni nigba ti a bá bi arólé kan ni ile ọba, okiki yoo kàn laaarin gbogbo awọn eniyan orilẹ-ède naa nitori rẹ̀, iroyin naa yoo si tàn ká gbogbo ayé. O gbọdọ jẹ́ ohun ajeji fun awọn amoye wọnyii nigba ti wọn dé Jerusalẹmu ti wọn kò si gbọ́ irọ́kẹ̀kẹ̀ kankan rara, ti wọn kò si ri ẹnikan ti o tilẹ dabi ẹnipe o mọ̀ pe a ti bi Ọba kan. Awọn amoye na mbère pe, "Nibo li ẹniti a bi ti iṣe ọba awọn Ju wà? nitori awa ti ri irawọ rẹ̀ ni ila-õrùn, awa si wá lati foribalẹ fun u." Dipo ti awọn eniyan naa i bá fi maa yọ̀ lati gbọ́ iru ihin rere bayii, idaamu ni o bá wọn. Ọba gbọ́ ẹru si ba a pe ẹnikan n bọ̀ wá gba itẹ lọwọ oun. O gbá ọ̀rọ ti awọn amoye yii wí gbọ́, dajudaju irú awọn eniyan nla bayii kò le rin irin-ajo ti o jin tobẹẹ lati wá wo ọmọ titun ti a bi ni orilẹ-ède miiran lai jẹ pe wọn gbagbọ́ pe Ọlọrun ni o fi ifihan pataki hàn fun wọn.

Ọba Hẹrọdu pe awọn olori alufaa ati awọn akọwe, awọn ti o mọ ofin, o si beere bi ohunkohun ba wà ninu asọtẹlẹ ti a kọ silẹ nipa ọba ti a o bi ni akoko yii; bi o ba si ri bẹẹ, nibo ni. Kò gbà wọn ni akoko ki wọn to ri idahun. Wọn kà a pe: "Iwọ Bẹtlẹhẹmu ni ilẹ Judea, iwọ kò kere julọ ninu awọn ọmọ alade Juda, nitori lati inu rẹ ni Bãlẹ kan yio ti jade, ti yio ṣe itọju Israẹli awọn enia mi."

Hẹrọdu ṣe bi ẹnipe oun pẹlu, n fẹ́ lọ wolẹ fun "Bãlẹ" naa ti awọn amoye wọnyii n wá lọ, o si pè wọn si ikọ̀kọ̀ o sọ ohun ti awọn wolii ti sọ fun wọn. O ni ki wọn lọ si Bẹtlẹhẹmu ki wọn si wá ọmọ-ọwọ́ naa, ki wọn si pada wá sọ fun oun ki oun ki o le foribalẹ fun un pẹlu.

### Irawọ ti N Ṣe Amọna

Awọn amoye naa tẹ̀ siwaju lẹsẹkẹsẹ, bẹẹni wọn tun ri irawọ naa niwaju wọn. Wò o bi ayọ̀ wọn yoo ti pọ̀ to lati mọ̀ pe Ọlọrun wà pẹlu wọn ati pe O n ṣamọna wọn sibẹ lọ si ọdọ Olugbala! Ọlọrun ki i fi ẹnikẹni ti o n fẹ ri Jesu silẹ ninu òkunkun, Oun yoo rán imọlẹ lati ṣamọna rẹ̀ si otitọ.

Bẹtlẹhẹmu jẹ́ ilu kekere kan ti kò jinna si Jerusalẹmu, kò si pẹ́ pupọ ki awọn amoye yii to de ibẹ. Nibẹ ni wọn ri imọlẹ irawọ iyanu nì ti n tàn lori ile naa gan nibiti Jesu wà pẹlu awọn obi Rẹ̀. Awọn amoye wọnyii, awọn eniyan nla ninu ayé, wọ inu ile ìrẹ̀lẹ̀ yii lọ wọn si foribalẹ fun Ọmọ-ọwọ́ naa. Wọ́n ṣi iṣura iyebiye ti wọn ti mú wá, wọn si bùn Ún ni awọn ọrẹ wọnyii pẹlu gbogbo ifẹ ọkàn wọn. Awọn ọkunrin wọnyii ti o ti orilẹ-ède miiran wá si gba ibukun Ọlọrun ṣaaju awọn alufaa ati awọn akọwe ti kò mọ Ọba wọn.

**Jesu Sá Asala**

Ọlọrun kilọ fun awọn amoye naa ni oju àlá pe ki wọn máṣe pada tọ Hẹrọdu lọ; wọn si bá ọ̀na miiran pada si ilu wọn. Hẹrọdu duro titi pe ki wọn pada lati wá sọ ibi ti oun gbé lè ri Jesu, ẹni ti o n fẹ́ pa fun un. Nikẹyin o wá mọ̀ pe wọn kò ni pada wà mọ́. Inu bi i lọpọlọpọ, o si rò pe oun ṣi le pa Jesu sibẹ. O paṣẹ fun awọn ọmọ ọdọ rẹ̀ lati pa gbogbo awọn ọmọ wẹrẹ, awọn ọmọ ọdun meji ati awọn ti o kere jù bẹẹ lọ, ni ireti pe ni ọ̀na bayii, dajudaju Jesu yoo pẹlu awọn ti a pa. Ṣugbọn Ọlọrun ti ṣe itọju Ọmọ Rẹ̀ bi o ti tọ́, O si ti wà ni Egypti pẹlu baba ati iya Rẹ̀, Josẹfu ati Maria, ni akoko ti iwa ìkà ti o buru jai yii n ṣẹlẹ ni Jerusalẹmu.

Ọlọrun ti kilọ fun Josẹfu pe Hẹrọdu yoo dá wahala silẹ; nitori naa ni ọjọ kan Josẹfu yọ́ sá jade pẹlu awọn ẹbi ti o kere yii o si mú wọǹ jinna réré kuro ninu ewu. Wọ́n jẹ́ alaini pupọ, o si daju pe ọrẹ lati ọdọ awọn amoye wọnni jẹ iranwọ fun wọn ni irin-ajo wọn lọ si Egipti. Nibẹ ni wọn wà titi Ọba Hẹrọdu fi kú. Josẹfu a maa tẹtisilẹ nigba ti Ọlọrun ba n sọrọ, a si maa gbọran si ohun ti o ba gbọ́. Nigba ti ọba yii kú, Ọlọrun sọ fun Josẹfu pe ki o pada si Judea, ki o si maa gbé ni ilu Nasarẹti, lati mú Iwe Mimọ́ ṣẹ pe a o pe Jesu ni ará Nasarẹti. Ọmọ naa si dagbà nibẹ. A kò tun gbọ́ nipa Rẹ̀ titi o fi di ọmọ ọdun mejila, ti a ri I ni Tẹmpili nigba ti O n kọ́ awọn ọjọgbọ́n ninu ọran Ofin.

**AWỌN IBEERE**

1 Nibo ni a gbé bi Jesu?
2 Ta ni kede ibi Rẹ̀?
3 Awọn wo ni o gbọ́ ikede naa?
4 Ki ni wọn ṣe nigba ti wọn gbọ́ ikede yii?
5 Awọn wo ni Ọlọrun tun fihàn fún pe a ti bi Jesu? Bawo?
6 Ki ni wọn ṣe nigba ti wọn gbọ́ nipa rẹ̀?
7 Nibo ni awọn amoye naa wá Jesu lọ?
8 Bawo ni wọn ṣe mọ ọ̀na ti wọn o kọjusi lati Jerusalẹmu?
9 Ki ni Hẹrọdu n fẹ́ ṣe si Jesu?
10 Bawo ni Jesu ṣe sá àsala?